**Lakaye Ọrọ**

ENITI o ba gba mi gbọ o gba Baba mi ti mbẹ l'ọrun gbọ. E o si mọ otitọ, otitọ yio si sọ nyin di ominira.



# Irohin Yoruba

No. 818 | FEBRUARY 8 — FEBRUARY 14, 1961 | KOBO MEJI (2D)






# ỌLAWỌYIN FESI SI ỌRỌ ALAKOSO IJỌBA IPINLẸ ARIWA

ỌLỌLA J. S. Ọlawọyin, Akọwe Agba Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni Ipinlẹ Ariwa, ti iṣe Aṣoju Ọffa ninu Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Ariwa, ti fesi si ọrọ ti Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello, Sardauna Sokoto, ti iṣe Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa sọ ni Kaduna ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejidinlọgbọn oṣu ti o koja yi.

Ọlọla Alhaji Ahmadu: ninu ọrọ rẹ ni Kaduna ṣe ikilọ fun awọn Ọba Ipinlẹ Ariwa ti nwọn wa fun ẹkọ ọsẹ meji lati igberiko kakiri Ipinlẹ Ariwa, ni ọjọ na pe Ijọba on ko ni jafara lati yọ kuro loye patapata, ọbakọba ti o ba jẹbi ẹsun iwa-ika ati itẹniloriba nipa, tabi ti o ba ṣe imẹlẹ lẹnu iṣẹ rẹ. Nitorina Ọlọla Ahmadu ni ko si aye fun iwa itẹniloriba, o ni ki nwọn sa gbajumọ iṣẹ wọn ni, bi bẹ ẹ si kọ ki nwọn kuku fi aye na silẹ.

Ọlọla Alhaji Ahmadu ṣe afikun ikilọ rẹ pe awọn ọba na nilati ni amu-mọra, ki nwọn ni suru ki nwọn si ma a ṣe otitọ nipa ilosi wọn pẹlu gbogbo awọn ara ilu. Ọlọla Ahmadu Bello si tun sọ 'pe o ti jẹ iwa awọn Ọba na lati ma a fi ọwọ sọ aiya fun awọn Kansilọ lori orişirişi nkan ki ọjọ awọn ipade Igbimọ to de, o ni aṣa yi gbọdọ pin" nitoripe ẹtọ ni fun awọn Kansilọ lati le sọ ẹdun ọkan wọn ni gbangba lori ọran ti o ba kan awọn adugbo wọn ninu ipade Igbimọ wọn.

**AWỌN KANSILỌ**

Alakoso Ijọba Ipinlẹ na si tun ba diẹ wi ninu awọn Kansilọ fun iwa pe nwọn ntu aşiri Igbimọ fun awọn oşelu, ati awọn ti nwọn nsọ ọrọ kan ni Ile Igbimọ, ti nwọn si tun nsọ nkan miran fun awọn ara ilu kakiri.

O ni iru awọn enia bẹ ẹ ko yẹ ni Aṣoju fun awọn enia wọn, o si tọ ki nwọn yọ wọn kuro ninu aye na. Ọlọla Alhaji Bello tun ṣe alaye pe, ẹkọ ti awọn Ọba na wa fun jẹ pataki pupọ, yio si ran wọn lọwọ daradara lati ṣe iṣẹ Ijọba adugbo wọn pẹlu irọrun.

Lori ero pe boya nwọn yio tete tu Igbimọ Aṣofin Ipinlẹ Ariwa ka, Alakoso Ijọba na ṣe alaye pe, on ko ti fi ọjọ si i lati tu Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Ariwa ka, nigbati on ba ṣe bẹ ẹ, on yio sọ fun awọn Ọba ti gbogbo ara ilu. O si ran awọn Ọba leti wipe, tituka Ile Igbimọ awọn Ijoye pẹlu, Alakoso Ijọba ni aṣẹ pipada si Ile Igbimọ awọn Ọba na wa lọwọ rẹ.

Nigbati Alhaji Haruna, Ọba Gwandu ndupẹ lọwọ Alakoso Ijọba na ni orukọ awọn Ọba yoku, o ni gbogbo awọn Ọba ni awọn gba imọran Alakoso na tọkan-tọkan. O si sọ fun Alakoso Ijọba na pe, dajudaju, ẹkọ ti o kọ awọn na wulo pupọ, o si tun gba Ijọba ni imọran pe, o yẹ ki Ijọba ma a fun awọn ni ẹkọ na lẹmeji lọdun, dipo ẹkanṣoṣo lọdun ti nwọn nfun wọn nisisiyi.

**ESI ỌLAWỌYIN**

Ninu esi rẹ si ọrọ Sardauna Sokoto, Ọlọla Ọlawọyin sọ pe ikilọ ti Ọlọla Alhaji Ahmadu ṣe fun awọn Ọba ati Ijoye Ipinlẹ Ariwa dara pupọ, o si bọ si eto, o ni ṣugbọn ikilọ na ko to. O ni o dabi igbati Ọlọla Alhaji Ahmadu fi ohun ti o yẹ ki o ṣe silẹ, ti o wa nṣe nkan miran.

Ọlọla Ọlawọyin ni ohun pataki kan ti Ọlọla Alhaji Ahmadu ni lati ṣe nisisiyi gẹgẹbi Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa ni pe, ki o ma jẹ ki awọn Ọba ati awọn Minista Alamojuto eto iṣẹ Ijọba ni Ipinlẹ

**(Wo oju ewe kẹrindilogun)**



Ọlọla J. S. Ọlawọyin



Ọlọla Anmadu Bello Alakoso ijọba Ipinlẹ Ariwa

# ATOKA

## WO


| | |
|---|---|
| Ọrọ Akibu Alarape | 5 |
| Akede Ọna Igbala | 6 |
| Mo ti di Aladura, nko ṣe ajẹ mọ | 8-9 |
| Bibeli Mimọ t'Ọrun | 10 |
| Itan Işẹdalẹ Ilerin | 12 |
| Iwọ ha ngba Awẹ rẹ l'ẹtọ bi? | 14 |
| Akiyesi Awọn Awo Irawọ | 15 |

# Rosiji ṣe ikilọ fun awọn ara ilu Kamẹrun lori ibo ti nwọn o di ni ọsẹ yi

OLOYE Ayọ Rosiji, Akọwe agba Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ṣe ikilọ fun awọn ara Kamẹrun nipa ibo ti awọn ara Iha Ariwa ati Iha Gusu ilu na yio di ni ọjọ kọkanla ati ọjọ kejila oṣu yi lori pe bi awọn ilu na yio pa ara wọn pọ di



OLOYE AYỌ ROSIJI

ọkanṣoṣo pẹlu ilu Kamẹrun ti o ti gba ominira kuro labẹ Ijọba Faranse ṣugbọn ti nwọn ko ni Ọba, tabi bi nwọn yio kuku faramọ ilu Naijiria gẹgẹbi nwọn ti wa tẹlẹ.

Ninu iwe ikilọ ti Oloye Ayọ Rosiji ṣe ni ọjọ'itu ti i ṣe ọjọ kini oṣu yi, o sọ pe ni ọjọ kọkanla oṣu yi awọn ara ilu Iha Ariwa Kamẹrun yio fi ibo wọn ṣe ipinnu nla kan, eyiti yio jẹ pataki-julọ ninu ipinnu miran nwọn ti nṣe ri.

**AYỌRISI IBO**

O ni ni ọjọ keji ẹwẹ ti i ṣe ọjọ kejila oṣu kanna, awọn ara ilu Iha Gusu Kamẹrun yio tun ṣe iru ipinnu bakanna.

Oloye Rosiji ni ayọrisi ibo na ni yio fihan bi awọn ara ilu Kamẹrun ba ni itẹlọrun si i, ti nwọn ba gba ominira, lati wa pẹlu Apapọ Ijọba Naijiria tabi lati wa pẹlu ilu "Cameroons Republic ilu ti ko ni Ọba. O ni ko si si ipinnu miran ti awọn ara ilu Kamẹrun fẹ ṣe lọjọ mejeji yi ju eyi ti a ti ṣe alaye rẹ ṣiwaju lọ.

**IFẸ ỌLỌRUN**

O ni ṣugbọn nigbati o jẹ pe ifẹ Ọlọrun ni lati da awọn ara Kamẹrun yi pọ mọ awọn ara Naijiria ti awọn ara ilu mejeji yi si ti jijọ nlo pọ bi ẹya kanna ati bi ọmọ iya kanna laisi ede-aiyede kan lati nkan bi ọgbọn ọdun sẹhin, ẹtọ gbogbo awọn ara ilu Naijiria ni paapa awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ti nwọn ngbadun iranlọwọ



J. N. FONCHA

★ ★ ★

ọpọlọpọ awọn ara Kamẹrun ti nwọn wa ni Iha Ariwa lati fẹ ire fun wọn ati lati gbadura fun wọn pe ki Ọlọrun ṣe Amọna wọn lati ṣe ipinnu ti yio ṣe wọn ni anfani pupọ.

Oloye Rosiji ni Ẹgbẹ Afẹnifẹre, ko fẹ ki awọn ara Kamẹrun lọ dapọ mọ awọn ti nwọn ko ba lo pọ ri: nitoripe ajeji ni nwọn yio jẹ larin awọn enia ti nwọn ko gbọ ede ara wọn ti nwọn le ma a fi sisẹ pọ. O si so pe awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ẹka Kamẹrun ati awọn alatilẹhin wọn ti nwọn wa ni Iha Ariwa Kamẹrun si ti ṣe ipinnu lati dibo lati wa pẹlu Apapọ Naijiria.

**ALAYE**

Ṣugbọn Oloye Rosiji ṣe alaye pe nitotọ awọn ara Iha Ariwa Kamẹrun ko ni itẹlọrun rara ni Iha na, nwọn si nfẹ lati gba ominira ti nwọn ba ti dapọ mọ Apapọ Naijiria. Gbogbo ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre jake-jado ni o faramọ ifẹ wọn na; nitoriti o dara to, ati pe gbogbo ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni yio si ma a ṣe atilẹhin fun wọn lori ọran yi titi ti ohun na ti nwọn nfẹ yio fi bọsi fun wọn dada.

Oloye Rosiji tun ṣe alaye siwaju pe bi awọn ara Iha Ariwa Kamẹrun ba lọ titori ainitẹlọrun papọ mọ ilu "Cameroons Republic" ti ko ni Ọba, eyi yio jẹ adanu nla fun wọn.

O ni nitori eyi ni Ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe fẹ ran wọn lọwọ ki ọran wọn ma ba a dabi ti ẹniti o ti inu iṣasun gbigbona ko si inu ina, eyiti rogbodiyan nla to wa ni ilu "Cameroons Republic" nisisiyi da silẹ.

# Aṣiwere kan wọ inu ṣọọṣi o si ṣa Woli Aladura kan ni ada

KABBA.

NIBITI Woli Aladura kan, Reuben Shenewa, ti Ijọ "Apostolic Church", Aiyegunlẹ-Gbẹdẹ ni agbegbe Ijumu. Ẹkun Kabba, ngbadura fun ọpọlọpọ awọn enia Ijọ rẹ lọwọ ninu Ṣọọṣi na, ni ọkunrin aṣiwere kan, Paul Ọlọrunmaiye ti nwọn fa fun Woli na pe ki o fi adura ṣe iwosan fun un, ba jade larin ọpọ awọn enia na pẹlu ada ti o mu-yanyan kan ni ọwọ rẹ, o si doriko ọdọ Woli ti o ngbadura fun wọn na taara.

Nigbati awọn Ijọ ri were yi pẹlu ada lọwọ rẹ ni nwọn ba bẹrẹ si sare kolu ara wọn pẹlu ariwo ibẹru nla ,ọpọlọpọ ninu wọn si yara gba oju ferese bọ sode. Ki Woli yi to gbojusoke lori ikunlẹ adura pe "kilode"? aṣiwere na ti la a l'ada ni atari latẹhinwa, nwọn si gbe Woli na lọ si Ile-iwosan Alaisan Aiyegunlẹ-Gbẹdẹ fun itọju.

Nigbati awọn ọlọpa mu aṣiwere yi, Paul Ọlọrunmaiye, de iwaju Adajọ Kotu awọn Ọdaran ni Kabba (Kabba Criminal Court) laipẹ yi fun ẹsun pe, o ṣa enia lọgbẹ. Adajọ na woye rẹ titi, o ni ki nwọn mu u lọ si Ile-iwosan fun ayẹwo awọn Dọkita.




# Ẹgbẹ Onimọto Ipinlẹ Iwọ-Orun nfẹ iranlọwọ Ijọba

IBADAN.

LẸNULỌLỌYI ni Ọgbẹni S. Agbolade Odukọya, Akọwe Ẹgbẹ awọn Onimọto ati Awamọto ẹkun Ipinlẹ Iwọ-Orun (Western Province Motor Transport and Drivers Union) ṣe ikede kan ni Ibadan nipa iwe ti nwọn kọ si Ijọba pe Ẹgbẹ awọn mbẹ Ijọba Ipinlẹ Idọ-Orun pe ki nwọn jọwọ ṣe iranlọwọ fun awọn lati da awọn enia lẹkun iwa aiyederu ti o wa ninu gbigba iwe-aṣẹ mọto-wiwa ti o gbojikan kakiri Ipinlẹ na nlaiiyi.

Orun ti o nṣelẹ nipa fifi iwe-aiyederu aṣẹ mọto-wiwa yi fun awọn alaimọkan ati awọn ti nwọn ko mọ mọto-wiwa dajudaju ni pe, nwọn nfi ọpọlọpọ ẹmi ṣofo nigbagbogbo ti ijamba mọto ba ṣẹlẹ lọwọ wọn loju ọna.

Akọwe ẹgbẹ na si fi ẹjọ sun wipe, ọpọlọpọ ninu awọn ọmọ-ẹkọṣẹ mọto-wiwa taara ti o wa ninu Ile-ẹkọṣẹ ẹgbẹ awọn ni nwọn ti salọ laiduro pari ẹkọ wọn, ti nwọn si ti lọ gba iwe-aṣẹ mọto-wiwa nibomiran ni ọna eru.

Ọgbẹni Odukọya si damoran wipe, ọna kanṣoṣo ti Ijọba le gba fi "wa ẹgbọ dakun" iwa itanjẹ yi ni pe, ki awọn ọlọpa ṣe alekun agbara wọn, ki nwọn si ko awọn arufin na timọle.

# IROHIN KAKIRI ILẸ YORUBA

# Ẹgbẹ IDU ni ki IPU gba pe ki awọn dibo titun ni Ijumu

NI ọjọ Aiku ti i ṣe ọjọ kejilelogun oṣu kinni ọdun yi ni awọn ọmọ Ẹgbẹ Dẹmọ ti Ijumu (Ijumu Democratic Union) ti agbegbe Ondo ṣe ipade ajọdun nla ni Ile-Oluji.

Nwọn sọ ọrọ pupọ lori bi ilu wọn yio ti ṣe ma a ni ilọsiwaju. Nwọn si ṣe eto nipa bi awọn yio tiṣe ma a mojuto bi gbogbo nkan ti nlọ si ni Ijumu.

Ọkan ninu awọn alakoso ẹgbẹ na ni Ile-Oluji Ọgbẹni Johnson Ajibikẹ ti o ti fi igbakan wa ninu ẹgbẹ 'Ijumu Progressive Union', ti o si jẹ koko kan ninu ẹgbẹ na mu imọran wa pe ki awọn kowe si ẹgbẹ 'Ijumu Progressive Union' (IPU) ti nwọn nṣe alakoso Ijọba Ibilẹ Ijumu pe ki nwọn gba ki Ijọba Ipinlẹ Ariwa tu Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ijumu ka, ki awọn si ṣe idibo miran.

Gbogbo awọn to wa ninu ipade na si fi ara mọ imọran yi, nwọn fi ohun ṣọkan pe ki ẹgbẹ IPU gba lati jẹki Ijọba Ipinlẹ Ariwa tu imọran na ka. Ẹsun ti ipade na ka si Ẹgbẹ IPU lọrun ni pe ẹgbẹ na lo da rogbo-diyan ti o wa ni ilu Ijumu silẹ nisisiyi, ko si si ohun ti o dara bi ki awọn tun ibo miran di, fun anfani ilu wọn.

Lẹhin ipade na ni awọn ọmọ Ẹgbẹ yi lọ si ile Ọba Alaiyeluwa Jegun Keji ti Ile Oluji, nwọn si ki i ku ewu ọdun titun.

## Giwa jẹ oye Majẹobajẹ ni Ifẹtẹdo

IFẸTẸDO-IFẸ.

OGUNLỌGỌ enia lo wa sibi aṣeyẹ ti awọn ara ilu ṣe ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu ti o kọja yi. Ọjọ na ni Balẹ, awọn Ijoye ati awọn Afọbajẹ fi Ọgbẹni Sule Ogunwunmi Giwa ọmọ Jagilegbo jẹ oye Majẹkobajẹ.

Ọgbẹni Sule Ogunwumi ni ẹni akọkọ ti yio jẹ oye yi lati igbati nwọn ti tẹ ilu na do ni nkan bi ọdun mọkandilọgbọn ṣẹhin, o si jẹ sanmari pataki larin ilu Oye ti o si jẹ na ni o tẹle awọn Iwarẹfa mẹfẹfa.

Fun odidi ọjọ meje ni awọn ara ilu fi ṣe aṣeyẹ na fun Oloye yi.

Awọn egungun ilu ati Jagilegbo paapa lati Ifewara wa ṣere nibi ajọyọ ifinijoye na.

Diẹ ninu awọn enia pataki-pataki ti o wa sibi aṣeyẹ ifinijoye na ni awọn Oloye J. A. Awogbade (Balẹ Ifẹtẹdo), Bamgboye (Balogun), M. A. Adeṣigbin (Ọtun), Akintunde (Ẹkẹrin), Oyeyiọla (Ẹkarun), Adetumbi (Aṣipa), G. Akinyọle (Osi), Dipọ Fayẹmi (Mọyẹ), Ọgbẹni James Ogunwande, Golu Makinwa, J. O. Idowu, S. O. Ọmọnubi, Kansilọ Akinjagboye; Iyaafin Esther Ọmọnubi, Phebean De Love, Ọgbẹni Ijiyẹmi (Ẹkẹrin Okeigbo), H. O. Ojuade, K. A. Adeyẹmi lati Ifẹ, I. O. Omiṣore, Lemọmu Agba Tijani O. Adefiṣayọ (Lemọmu Ilu) ati Iyalode ilu.



ỌGBẸNI SULE OGUNWU MI GIWA

## Awọn mẹta jẹ oye ni Ilọra

ILỌRA LẸBA ỌYỌ.

IROHIN ko to afojuba ni ti aṣeyẹ ọjọ ti Balẹ Ilọra nfi awọn enia pataki mẹta jẹ oye ilu. Awọn na ni Ọlọla S. A. Eyitayọ ti iṣe ọkan ninu awọn aṣoju Igbimọ awọn agbaoṣelu (senate), Ọgbẹni J. A. Moshebọlatan ati Ọgbẹni Ezekiel Ogunrombi.

Nwọn fi Ọlọla Eyitayọ jẹ Ẹkẹrin Ilọra, Ọgbẹni Moshebọlatan jẹ Bariyun, Ọgbẹni Ogunrombi si jẹ Ọdọfin.

Eto ifinijoye na bẹrẹ pẹlu adura lati ọdọ Ọgbẹni D. K. Shangontẹ, lẹhinna ni Ọlọla S. O. Kọlade, ọkan ninu awọn aṣoju ninu Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria (House of Representatives) sọ ọrọ iyanju.

Lẹhin eyi ni Lemọmu Ilọra ṣe adura lẹkun fun ilọsiwaju ilu Ilọra ati Ipinlẹ Iwọ-Orun. Nigba na ni Alaiyeluwa D. A. Ọparinde, Balẹ Ilọra wa bẹrẹsi ṣe eto oye na le awọn Oloye titun na lori. Nigbati o pari rẹ tan ni ogunlọgọ awọn enia to wa nibi aṣeyẹ na bẹrẹ ijo ati ariya.

Awọn enia to wa si ibi aṣeyẹ na pọpupọ, nwọn si wa lati Awẹ, Fiditi, Akinmọrin, Jobele Imenni, Iwo, Ogbomọshọ, Ẹdẹ, Oshogbo, Ile-Ifẹ, Ibadan, Ghana, Akurẹ, Abẹokuta, Isẹyin, Shaki, Ilaro, Irẹpọ, Eko ati Ijẹbu.

## Ọmọ-ọba Onirẹssa jalaisi

NI ọjọ kẹtadinlogun oṣu kini ọdun yi ni Iyaafin Alepata Olagbenro, ọmọ Onirẹsa ti Irẹsa fi aiye silẹ. O gbe ọgọfa ọdun laiye. Awọn ọmọ rẹ si jẹ mẹrindinlọgbọn.

Awọn enia pataki-pataki ti o wa si ibi isinku rẹ ni Arẹ ti Igboho, Baṣọrun Okere, Alfa Sanni Balogun, Sanusi Maka Onilu, Kansilọ Gbadamọsi ati Ọmọ-ọba Oloyede Ọladeji. Ọmọ-ọba Mopelọla Oloyede ti o wa ni ilu Oyinbo kọ iwe lati kẹdun.

Ọmọ-ọba Oloyede ki gbogbo awọn ara Igboho ti o mu isinku na miringindin Oluwa jẹ ki ẹhin oku na dara o.

Awọn Iṣaka ati Rorẹ fẹrẹ jẹki o padanu ninu Idije Ẹwa rẹ



1. Mary ni nwọn ni igbẹkẹle si pe yio bori ninu Idije Ẹwa ni ọjọ Satide. Ṣugbọn ni ọjọ Tọsde o ba a lẹru lati ri i pe Iṣaka ati rorẹ ti su yọ loju rẹ lojiji.

2. Mary bu s'ẹkun pe, "ko si ireti fun mi mọ." Iya rẹ sọ pe, "Maṣe ṣe iyọnu ọmọ". "Mo mọ oogun ti yio tete lé awọn iṣaka ati rorẹ lọ—Mentholatum."



3. Mary fi Mentholatum ti o npa irora ti o si ngmu oju kutu pa oju rẹ . . nigbati yio fi Satide awọn iṣaka ati rorẹ oju rẹ ti lọ. Awọ ara rẹ fa ni mọra ju ti atẹhinwa lọ.

4. "O wa di ojulowo arẹwa ọmobirin gan an". Mary gbọ ti ọkan ninu awọn onidajọ idije-ẹwa na sọ nigbati nwọn fun un ni ẹbun ipo Kini pe "Awọ ara ọmọ yi ma a kuka jọlọ pupọ." Mary ronu pe "Ọpẹlọpẹ Mentholatum" bi o ti tẹriba fun Onidajọ na.



Werewere ni awọ-ara yio di jijọlọ yio si kunna pada nigbati o ba fi Mentholatum aiura, awora, adẹra pa a. O nṣiṣẹ bi idan—o nwo awọn ẹgbo, iṣaka ati rorẹ san werewere, o daju ko si lewu. Ri i daju pe, Men-tho-lay-tum gan an ni o ra ti o wa ninu awọn agolo ati idẹ bi iru iwọnyi. Maṣe ra awọn adamọdi.

Awọn ti o nṣe e nikan ni

MENTHOLATUM CO. LTD

(Est. 1889), Slough, England

MENTHOLATUM

IPARA TI O DARA JU

## ỌRỌ AKEWI : Lati ọwọ ỌMỌ-ỌBA AKIBU ALARAPE, IBADAN

# ALUBARIKA LOJU (4)

OLOTU, kara o le o. Mo ro wipe gbogbo wa ni yio ti ranti wipe ibiti ọrọ wa ni de ni wipe Ogboni na sọ fun iyawo rẹ wipe, nṣe ni ki o ronu si nkan miran lati fi kẹwọ sọ wipe on ni o fa ipinya larin awọn.

Iyawo na si dahun wipe "ki iṣe bẹ ẹ rara, nkan ti mo ro ki ngto sọ wipe asiko tito fun ipinya larin wa ni wipe; mo ṣẹṣẹ mọ nisisiyi bayi ni, wipe, iwọ ko tilẹ mọ nkan ti o nlepa tabi ti iwọ nfẹ lati ni.

"Bẹẹ si ni, iṣoro nla ni o wa f'ẹnikẹni ti o ba nlepa ohunkohun, ṣugbọn ti oluwarẹ ko mọ nkan na ti o nlepa rẹ, nitoripe, bi nkan na ba tilẹ wa ni atẹlẹwọ oluwarẹ bayi, dajudaju, oluwarẹ ko ni mọ ọ rara, nipa aimọkan rẹ.

### IBUKUN ỌLỌRUN

"Nkan ti o mu mi sọ bayi ni wipe, ni akoko kan ti iwọ nsọ wipe Ibukun Ọlọrun ni iwọ nwa, inu emi paapa dun nigbana nitoripe nkan ti o dara ni eyi.

"Ṣugbọn lẹhin eyini ni mo ṣe akiyesi wipe iwọ ko mọ nkan ti nwọn npe ni Ibukun Ọlọrun na ti iwọ nwa atipe, iwọ ko tilẹ si fẹ mọ ọ rara.

"Iti bẹ ẹ kọ ni, nṣe ni o ba kuku bi baba rẹ lere loju ala wipe, kini nkan na gan an ti o njẹ Ibukun Ọlọrun, nigbati o ṣe wipe baba rẹ na ni o juwe fun wa wipe ki a lọ gbẹlẹ ni idi igi kan ki a si hu owo ti o wa nibẹ fun anfani ara wa. Ti baba na tun wa padida ti o tun sọ fun ọ wipe, ko si Ibukun Ọlọrun nibẹ!"

Ọmọdekunrin na si fesi si ọrọ iyawo rẹ bayi wipe, "nisisiyi ni iwọ to sọrọ dasilẹ gẹgẹ bi ọlọgbọn enia, ṣugbọn iwọ ti kọkọ fi ara han gẹgẹbi alaimọkan nigbati iwọ nṣe idajọ lori nkan ti iwọ ko mọ, atipe, iwọ ko si bere nipa nkan na ti nwọn npe ni Ibukun Ọlọrun.

"Ṣe nigbati emi ba ti sọ iru nkan ti nwọn npe ni Ibukun Ọlọrun, ṣebi nigbana ni o to di ẹtọ fun ọ lati gba mi ni iyanju bibere nkan na lọwọ baba mi loju ala nigbamiran?

### OMULẸ-MOFO

"Ṣugbọn ju gbogbo rẹ lọ,ngko ni fa ọrọ na gun lọ titi mọ ki emi pẹlu rẹ ma ba a di iru kanna. Nitorina nkan ti mo fẹ sọ fun ọ ni wipe, dajudaju, emi mọ kan ti mo nṣe, to bẹ ẹ ti mo fi mọ wipe nkan na ni o dara ju.

"Nitorina ni mo si ṣe mọ wipe bayiowu ki kinikan le pọ to, bi Ibukun Ọlọrun ko ba si nibẹ, omulẹ-mofo ni nkanna jasi, nitoripe airotẹlẹ ni nkan na yio parẹ.

"Bẹẹ si ni, ki enia wa laini nkankan dara ju ki enia ti ni nkan tẹlẹ ri, ṣugbọn ki o si tun pada di alaini rara mọ lọ. Bakanna, si wẹ, bayiowu ki nkan le kere to, bi Ibukun Ọlọrun ba ti wa ninu kan na, laiṣe ani-ani, nkanna yio tubọ ma a pọ si i, to bẹ ẹ ti ko si ni tan mọ titi aiye.

"Nitorina, bi iwọ ba mọ wipe bayi ni Ibukun Ọlọrun ri, dajudaju iwọ yio mọ nigbana wipe ẹnikẹni ti ko ba le ni ifarada lati ma a reti Ibukun Ọlọrun tabi lepa rẹ, ni gbogbo igba ni irufẹ enia bẹ ẹ yio ma a ke abamọ.

### IDENA ILỌSIWAJU

"Nitorina, lẹhin alaye diẹ ti mo ṣe yi, bi o ba ṣi wa lori ero rẹ kanna wipe akoko yi ni ipinya yio de ni arin wa, emi ko kọ fun



AKIBU ALARAPE

* * *

ọ rara, nitoripe, bi eyi ba ri bẹ ẹ, nkan ti yio wa ni ọkan mi ni wipe, boya, iwọ ni ẹni na ti o nṣe idena fun ilọsiwaju mi lati ri Ibukun Ọlọrun gba lati iye ọjọ yi wa."

Bayi ni Ogboni na pari ọrọ rẹ, ti iyawo rẹ na si mi kanlẹ hun un, ti o si wipe, "ko buru, mo gbọ gbogbo ọrọ nyin, o si ye mi dada, nisisiyi ni emi na yio tubọ ni suru diẹ si i, nitoripe, ni asiko ti enia ba nfẹ sọ ireti nu bayi na ni aranṣe Ọlọrun ma a nde".

### IBUKUN ỌLỌRUN DE

Bayi ni awọn mejeji ti ṣe pari ọrọ na larin wọn, ti nkanna si tun pada si aye irẹpọ ti nwọn ti jijọ wa tẹlẹri, ti nwọn si mba nkan wọn lọ gẹgẹbi ti atẹhinwa.

Ọpọlọpọ igba ni nkan nlanla miran si tun nṣẹlẹ larin wọn ti nkanna si tun njasi bakanna.

Bayi ni gbogbo nkan na nṣẹlẹ titi ti o fidi alẹ ọjọ kan bayi nigbati ọmọde yi tun la ala ri baba rẹ bakanna, ti baba na si tun ẹsọ fun un wipe, bi ilẹ ba ti mọ, ki o lọ si inu iyara ti on gbe nsun ni igba-aiye on. O ni bi o ba ti wọ inu iyara na, yio ri apo kekere kan ni kọrọ iyara na ni apa ọtun.

Atipẹ, bi o ba ti tu inu apo kekere na wo, yio ba owo kan bayi ninu apo na ki o mu owo na nitoripe Ibukun Ọlọrun wa lara owo na, to bẹ ẹ ti Ibukun na ko ni apejuwe.

Baba na si tun sọ fun ọmọ rẹ pe, "lati igbayi lọ, iwọ yio ni igbadun pupọ ninu aiye to bẹ ẹ ti iwọ ko fi ni ri inira mọ ni ile aiye lailai."

(KOI TI PARI O)

# Owe ilẹ Yoruba

*(Lati ọwọ Emman. Akande, Oniṣegun Iroko)*

BI a ko ba gbe gba oju rẹ lọ, ko le bọ si oju rẹ, lo difa fun iwọfa ti o ni on yio jogun olowo on. Iwọfa ni koko ti o wa ni isalẹ odo ti o jẹ ti olowo on, on ni on yio mu, awọn ọmọ-olowo ni baba ko bi iwọfa, iwọfa ni awọn jọ ro oko na ni. Awọn ọmọ olowo ni owo ti iwọfa nsin ni yio ya f'owọ mu. Nwọn ba ni ki o ma a mu owo na, ni Iwọfa ko ba san owo na mọ.

Ohun ti a fẹ, ati ohun ti a ko fẹ, bakanna ni i dunni mọ. Ohun ti a fẹ ti ọwọ wa ko ba si tẹ ẹ, yio ma a dun wa, ohun ti a ko si fẹ, ti a ba ri i yio ma a dunni bakanna.

Iwa ado ni i mu ni fi akukọ adiẹ bọ ọ, akeregbe baba rẹ omi ni nwọn fi npọn l'edo.

Mama fi ọran mọ ara rẹ lọrun, nwọn ni ekiri ẹran mẹfa ṣẹ ku meji, o ni on o kuku de ibẹ, o ni ṣugbọn iyọ ko dun ẹran na. Nigbati kò de ibẹ, o ṣe mọ wipe iyọ ko dun ẹran na?

Iritori ni imọtomọ ni nwọn ṣe fi ọṣẹ ogoje wẹ igi-imu kan.

Koro ninu iyara, koro ninu iyara, ikọ ti ao ko sinu iyara iya ẹni, a ko le ko si ti orogun iya ẹni bẹ.

Ọmọ ti o ni baba on ko mọ erupẹ ṣu, ọrọ lo fẹ gbọ. Baba rẹ sọ fun un pe, ori rẹ bamba-bamba yẹn oru ni on ṣu u.

Ẹniti Ọba ko bi, ti Ọṣọrun o ya, ti o ni on gbẹdẹgbẹdẹ lọṣọ, ojo lo pa a ti oko de.

Alaigbọn obirin ti o ni onigbese ni ọkọ on, tani o da gbese na si ọkọ l'ọrun?




# Akede Ọna Igbala

## Ina Atupa wa nku lọ

"BABA, atupa wa nku lọ!" ni ọmọdekunrin kekere kan nsọ fun baba rẹ nigbati awọn mejeji wa ninu ile ti atupa ti nwọn gbe si ọdọ wọn nku lọ.

Ni alẹ ọjọ kan ni ọkunrin kan ati ọmọ rẹ wa ninu ile ti nwọn si gbe atupa wọn si ọdọ pẹlu ina ninu rẹ. Ṣugbọn bi o ti pẹ diẹ ni atupa na ko tun jo soke to bi o ti njo tẹlẹ mọ, okunkun nwọ inu ile. Baba ọmọ na ko si tete fiyesi ilẹ ki ọmọ rẹ ọkunrin ti o duro ti i na to kiyesi pe atupa ti awọn gbe kalẹ ni nku lọ bẹni okunkun si nwọ inu ile.

Baba ọmọ na yaa dide nibiti o joko o si yara lọ fi epo sinu atupa na ki o le tubọ jo soke bi ti atẹhinwa ki okunkun ma ba a ri aye wọ inu ile wọn.

### IRẸWẸSI DE

Bayi ni irẹwẹsi ti de ba ọpọlọpọ ọkan awọn enia ninu ijọ Ọlọrun loni tobẹ ti nwọn ko tun ni itara ninu ẹmi ati gbadura mọ. O si ti rẹ gbogbo awọn alagba ijọ ninu iṣẹ Oluwa nitori ifẹ owo ati awọn ohun aiye yi ti gba ọkan wọn kuro ninu ifẹ Ọlọrun bẹni awọn oniwasu ko tun ni ẹmi isọji mọ lati fi gbe ijọ Ọlọrun dide.

Gbogbo ọkan awọn ijọ si kun fun iwa ainani ilana Ọlọrun. Nwọn ko tun ri aye lati gbọ ti Oluwa mọ, bẹni ṣọṣi lilọ ni ọjọ ọsẹ di iṣoro nitori nwọn ti pa ina emi ti o wa ninu ọkan wọn.

Irohin ko to afojuba ni iṣẹ ribiribi ti awọn enia wa ti o kọkọ gbagbọ ṣe, fun ẹmi gbigbona ati itara ti nwọn ni si iṣẹ Ọlọrun ni akoko ti wọn fun a ti tan Ihinrere Ọlọrun kalẹ. Awọn ti nwọn gbagbọ ninu ipọnju ati idamu inunibini lati ọdọ awọn enia ṣugbọn sibẹsibẹ bi ago ti nfi ara kan ara wọn bẹni gbogbo wọn yio ti ma sare lọ si ile dura wọn.

Bi o ti le jẹ ohun iṣoro nitori awọn ọta, nwọn fi ori ti i nitori imọlẹ Jesu Kristi ti nwọn ni ninu wọn. Nigbagbogbo ni nwọn nkun fun ẹmi Mimọ ti nwọn si ma nfi ara wọn fun isin mimọ Ọlọrun.

### ADURA, ẸBẸ

Bakana ni nwọn fi ara wọn fun adura ati ẹbẹ niwaju Ọlọrun, nwọn si ni igbẹkẹle pe Ọlọrun yio ṣe ohun ti awọn ba bere ni orukọ Jesu Kristi. Ina ẹmi wọn ko fi igba kan ku bẹni agbara ẹmi mimọ Ọlọrun ko si fi igbakan fi wọn silẹ.

Jesu Kristi paapa fun ara Rẹ ni o pe awa onigbagbọ ni imọlẹ, ti o si sọ fun wa lati ma a tan an nigbagbogbo ninu okunkun aiye yi. Ṣugbọn bi imọlẹ na ba lọ silẹ Eṣu yio raye wọ inu ile lati ṣe iṣẹ ibi rẹ, yio si mu ọpọlọpọ awọn enia kọsẹ.

Ṣugbọn bawọnyi yio ti ri fun wa nigbana, kini yio si jẹ iyọrọsi gbogbo lsalaa ati iṣẹ wa ninu Jesu Kristi, gẹgẹbi ọmọ lẹhin?

O to akoko fun ẹnikọọkan wa lati fi epo si inu atupa wa ki a si mu gbogbo awọn idọti ti o wa ni oju ati ara atupa wa kuro ki o le riran kedere siwaju si i. Eyi ni lati mu gbogbo awọn ẹṣẹ kekeke ti o rọ mọ wa ti o si ndi wa lọwọ lati le ni irẹpọ pẹlu Ọlọrun wa kuro, ki a si mura lai ma a gbe ninu Kristi ju bi a ti ngbe ninu Rẹ tẹlẹ lọ, ki a si jẹ ki Ọrọ Rẹ ma a gbe ninu wa nigbagbogbo.

Isọji yio bẹrẹ ninu ile wa, ninu iṣẹ wa ati ninu ijọ wa pẹlu. "Bi ẹnyin ba ngbe inu mi, ti ọrọ mi ba si ngbe inu nyin, ẹ o bere ohunkohun ti ẹ ba fẹ, a o si ṣe e fun nyin" (Johannu 15: 7).

### PA IDIWỌ TI

Ohun ti o kan iwọ ati emi loni ni pe ki a mura giri ki a si ṣe iriju rere fun Jesu Kristi ẹniti o pe wa sinu imọlẹ ki a maṣe jẹ ki okunkun ri aye wọ inu igbe-aiye wa, ki a ma ba a di ẹni igbagbe niwaju Ọlọrun.

Ẹ jẹki a pa awọn ohun idiwọ gbogbo ti si apakan ati awọn nkan ti ndi ina ẹmi wa lọwọ lati jo soke ninu iṣẹ Oluwa.

Njẹ atupa rẹ ko ha nṣe iṣẹ imọlẹ bi, ti ina ẹmi rẹ ṣe nku lọ pẹlu ẹru ẹṣẹ ti iwọ fi npa a? Ọrọ Ọlọrun sọ fun wa pe awa ko gbọdọ pa ina ẹmi wa, eyi ni pe lati ma fi awọn iwa buburu ti o wa ni inu wa mu ẹmi Mimọ Ọlọrun binu.

Jesu le mu ki o mura loni lati kuro ninu ẹmi irẹwẹsi. Jesu nfẹ lati fi epo si atupẹ rẹ. Ki Ọlọrun le ran isọji si ọkan rẹ lati gbe ọ dide kuro ninu orun ẹṣẹ. "Ẹ maṣe pa ina Emi" (I Tessalonika 5: 19).

# Awọn onisẹ Ọlọrun bẹ Olotu wo

NI arọ ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu ti o kọja yi ni awọn onisẹ Ọlọrun, ti nwọn nlọ bẹ ilu Ghana wo ya si ọdọ Olotu iwe Irohin Yoruba ni ile iṣẹ itẹwe Irohin Yoruba ni Elephant House ni 214 Broad Street, Lagos.

Awọn Ojiṣẹ Ọlọrun na ni Evangelist J. J. Akande, Ogbomọshọ, Apostle E. O. Akinrele, Supervising Prophet, Kaduna, Senior Apostle J.J A. Adegoke Ife, Ọgbẹni E. O. Bankole, Forestry Dpte., Ilọrin, Ọgbẹni J. O. Daniel, Treasurer Ilọrin N.A. ati Ọgbẹni P. A. Oyeniyi, Gaskiya Cor. Zaria.

Nigbati awọn Ẹni-Ọwọ na ki Olotu tan ni nwọn wa ṣe alaye fun un nigbati nwọn nfi ọrọ-jomitoro ọrọ pe: awọn fẹ lọ ṣe ibẹwo awọn enia Ijọ wa ni, wọn ni Ghana Oke-Okun awọn ko si ni i pẹ ni ohun ju ọsẹ kan lọ ki awọn to o pada si ile (Naijiria).

Ọkọ arefo o, alọ a dara, abọ a sunwọn o. Ipade wa bi oyin o.



# Awọn ọmọ Ararọmi Obu ṣe ẹyẹ fun Moses Adetuga Adedugba



ESẸ gbogbo ọmọ ibilẹ Ararọmi-Obu to wa l'Eko ati awọn ti ẹbi ati ọrẹ Ọgbẹni Moses Adetuga Adedugba lo pe ṣọṣọ si Ebute Ọkọ-ofurufu ni Ikẹja ni owurọ ọjọ Aiku ti i ṣe ọjọ kẹjọ oṣu kini ọdun ti o kọja yi lati wa pade Ọgbẹni Adedugba na ti o de lati ilu Gẹẹsi nibiti o ti lọ koṣẹ agbẹjọrọ (lọya) ni kikun ti o si yanri iṣẹ kikọ na. On ni o jẹ ọmọ Ararọmi- Obu akọkọ to gba oye agbẹjọro. Aworan oke yi ni ti awọn ẹbi ati ọrẹ lọya titun na. Ọgbẹni Moses Adedugba jẹ ọmọ Oloye Odunwo Joseph Adedugba, Ọmọ-ọba atunrin ti ilu Ararọmi-Obu na, on lo si wa ni ipo kẹrin lati ọwọ ọtun ninu awọn to joko.




DA

INU-RIRUN DURO

Nigbati o ba ni irora ninu ikun rẹ, ohun ti o nfa idi rẹ nigbagbogbo ni pe omiro ti pọju nibẹ. Omiro yi ni o nfa arun-inu, inu-kikan-ni ati airi-igbẹ-ya.

Ẹ ṣa ti mu egbogi Phillip's 'Milk of Magnesia' diẹ .........yio si ko rirogun omiro na kuro, a si le irora na lọ werewere. Yio fun okun-inu lagbara lati ti gbogbo nkan ti o nfa irora na jade kuro lara.

Ko lewu, o rọrun lati lo, o si tu ni lara.

'MILK OF MAGNESIA'

Awọn ti o nṣe e ni

PHILLIPS

ODARA FUN GBOGBO ẸBI





## Adọtadinlẹgbẹta enia yege ninu ede Yoruba

IBADAN.

LENULỌLỌYI ni awọn adọtadinlẹgbẹta (560) enia yege ninu ẹkọ iwe Ede Yoruba ni Ibadan, alabojuto ẹkọ Yoruba si fun ọkọọkan wọn ni iwe-ẹri pe o mọ iwe Yoruba kọ dada o si mọ ọ ka bakanna.


Ẹ ma a ka Iwe
IROHIN YORUBA
nigbagbogbo fun
irohin aladun


## Alapara Ibadan



GẸGẸBI ẹ ti ka ninu iwe "Irohin Yoruba" ti ọsẹ ti o kọja, Alapara Ibadan wa ni ilu Ghana, a nṣe ireti rẹ ninu ọsẹ yi. Ti o ba ti pada de, ẹ o mã a gbọ gbogbo nkan ti o ba ba bọ ilu Aganyin (Ghana).

# •Ma nko





Awọran oke pata-pata yi
ni ti igbati Lydia nfi
ohun ija rẹ ninu iṣẹ ajẹ
han. Ohun ija na ni o ko
soke ni ọwọ mejeji rẹ yi.
Aworan oke ti o tẹle ti akọ-
kọ ni gbogbo ohun ija
Lydia ti o fi nṣiṣẹ ajẹ, ti o
si ti ko silẹ lati idi agbọn
ni Okun nigbati Ẹni-ọwọ
S. O. Ọmọnubi "Doctor D
Love" ti gbadura kikun le
lori tan. Aworan ẹgbẹ y
ni ti igbati Ẹni-ọwọ S. O.
Ọmọnubi ngbadura kikan-
kikan le Lydia lori ni ọjọ t
nwọn mu u wa fun iwo-
san inu-hiho (belly trou-
ble) lẹhin igbati o ti f
iṣẹ ajẹ silẹ.

# ... ti di aladura, ... şe ajẹ mọ'







NINU iwe "Irohin Yoruba" ti ọsẹ ti o kọja, awọn onkawe wa ni anfani a ti ka nipa Omidan Lydia Abọdunde, ọmọ ọdun mọkandinlogun ti o ti gba ajẹ, ti o si ti fi ẹgbẹ awọn ajẹ na silẹ nipa agbara adura ti Ẹni-ọwọ S. O. Ọmọnubi, Olori Oniwasu ti Ijọ "African Independent Church", Şomolu, şe fun un nigbati nwọn mu u wa si ọdọ rẹ ni ile Adura wọn.

Lọsẹ ti o kọja na ni a şe ileri pe a o sọ iyoku ọrọ ti Lydia sọ nigbati on pelu Ẹni-ọwọ Ọmọnubi wa sọdọ Olotu iwe "Irohin Yoruba". Eyi ni iyoku ọrọ Omidan Lydia Abọdunde na:

"Gẹgẹbi alaye ti mo ti şe fun awọn oniwe irohin miran ki nto de ọdọ nyin, o yẹ ki ntun şe e pelu fun anfani awọn onkawe iwe "Irohin Yoruba".

"Nwọn bi mi ni ilu Gbọngan ni Ipinlẹ Iwọ-Orun ninu oşu kerin ọdun 1941. Baba mi ati iya mi ati awọn ẹbi obi mi na si wa ni ilu Gbọngan na titi di bi mo ti nsọ ọrọ fun nyin yi. Gẹgẹbi mo ti wi, orukọ baba mi njẹ Jacob Ọdunlade, orukọ isami ti iya mi si njẹ ni Alice. Mo ranti iya mi agba daradara. Ẹnikan ko le şe apejuwe rẹ fun mi ki nto mọ o ti o ba şe pe o wa laiye ni. Şugbọn o ti jalaisi.

**ỌMỌ MẸRIN**

"Ọmọ mẹrin ni Ọlọrun fi ta a lọrẹ, awọn meji jẹ ọkunrin, awọn meji yoku si jẹ obirin. Ọkan ninu awọn obirin na ni iya mi. Iya mi agba na ni awọn ọmọ-ọmọ pupọ, şugbọn ninu gbogbo wọn emi nikan ni o fẹran pupọ-ju, nitori emi ni ma a nta ọja fun un.

"Iya mi agba na ti ku nisisiyi o ti to ọdun mẹrin Oyinbo, şugbọn ki o to ku ni o ti fun mi ni agbara awọn ajẹ. Nko mọ nipa agbara awọn ajẹ tẹlẹtẹlẹ afi igbati o fun mi ni awọn nkan na. Bi o ti şe fun mi ni yi: Mo sun ni alẹ ọjọ na ninu ile rẹ, nigbati o si di ọganjọ oru ni o ji mi lati oju orun. O pe mi, mo si da a lohun.

"Nigbati mo da a lohun tan ni o ba dubulẹ le mi mọlẹ, ni o ba pọ nkankan si'mi lẹnu. Mo gbe nkan na mi lẹsẹkanna, nko mọ nkanna, nitori gbogbo rẹ dabi igbati mo wa loju ala. Şugbọn mo mọ pe mo gbe nkan mi. Nigbati mo ti gbe nkan na mi tan ni iya mi agba sọ fun mi pe on ti mu mi wọ ẹgbẹ awọn Iya. Lati igba na ni mo ti di ajẹ ti mo si ti mba awọn iyoku mi şe ajọ. Ọjọ mẹsan-mẹsan ni ipade wa, ni deede agogo mejila oru ni a si i ma npade. A nşe ipade na titi di agogo mẹta ọganjọ. Ninu ipade yi ni a ti ma a nşe eto ati pinnu işẹ ibi wo ni a o şe, ati pe tani a o şe e le lori. Ni ibi ipade yi ni a ti nsọ tani a o fi şe ase.

**ỌMỌ ẸGBỌN MI**

"Lati igbati mo ti wọ ẹgbẹ yi o ti di enia mejidinladọrin (68) ti mo ti ni ọwọ ninu iku wọn pelu awọn ẹlẹgbẹ mi. Şugbọn nigbati o şe, emi na si i tẹ lọdọ olori ẹgbẹ wa ni Gbọngan. Nwọn pinnu pe awọn yio pa ẹgbọn mi (ti o jẹ anti fun mi), nitori o jẹ enia rere, o si jẹ onisowo ti o ni owo lọwọ tị o si fẹran mi. Mo bẹ wọn pe ki nwọn darijin ẹgbọn mi na, şugbọn nwọn ko gba si mi lẹnu. Mo bẹ wọn gidigidi, nwọn si gba simi lẹnu nigbati mo sọ fun wọn pe ngô fun wọn ni ọmọ ẹgbọn mi na fun pipa. Nwọn pa ọmọ ẹgbọn mi, lati igba na ni inu mi ti bajẹ, nitoripe mo fẹran ọmọ ẹgbọn mi na pupọ.

"Lati igba na ni mo ti pinu pe ngo fi ilu Gbọngan silẹ. Nigbati ẹgbọn mi si mbọ wa si Eko ni nkan bi oşu kerin sẹhin, mo ba a wa si Eko. Awọn ẹgbẹ na si gba mi si ijọ ti Bariga. Ni ilu Bariga awọn ẹlẹgbẹ mi to wa nibẹ to igba (200), ni Idi-Iroko ni a si ma a nşe ipade wa lọjọ mẹsan-mẹsan gẹgẹbi ti Gbọngan.

"Lẹnu ọjọ mẹta yi nko şe deede mọ nibi ipade wa. Lati nkan bi ọsẹ mẹta nisisiyi, nko tilẹ wa si ipade na mọ. Iya Ẹgbẹ wa ni Bariga şe oye nipa aişedeede mi yi, o si ti pinnu lati jẹ mi niya. Orukọ Iya Ẹgbẹ wa na njẹ Iya Alatẹ. Ninu "şeriya" ti nwọn da fun mi nipe nko gbọdọ wa si ibi ipade awọn ẹlẹgbẹ mi ni Bariga mọ, nwọn si ti yọ mi kuro ninu ijọ ti Şomolu ati ti Mushin.

**KO SI ẸIYẸ AJẸ**

"Eyiti o tilẹ buru julọ, nwọn ti da ọjọ iku mi, nwọn si ti fi ọjọ iku mi na si asiko Ọjọ Ajinde—ninu oşu kerin ọdun yi. Ko si nkan ti njẹ ẹiyẹ ajẹ. Ajẹ kan ko ni ẹiyẹ rara. Işẹ ajẹ jẹ işẹ ibi pupọ, ki i şe ẹiyẹ ni o ngbe enia kiri, emi ni. Bi nkan na ba fẹ de, yio dabi ẹfin, yio si ko si enia lọkan, yio ma a ru lọkan oluwarẹ. Yio si ma a ti oluwarẹ kiri titi igbati oluwarẹ ma fi şe işẹ ijamba, ti oluwarẹ ba wa şe e tan ni oju oluwarẹ yio wa wa silẹ .. Ohun ija mẹta ni ajẹ ni:—Agadangodo, kokoro ati igi kan ti nwọn şe bi ada. A nlo awọn agadangodo ati kokoro fun lati le mu enia ki o ma mọ ohun ti o nşe, a si nfi igi alagada yi lu enia pa ni.

" Nisisiyi, mo dupẹ ti ara ati emi mi ti bọ lọwọ awọn ajẹ, ti mo si ti di enia gidi pada lagbara adura ti nwọn gba le mi lori. Nko ni ijaiya mọ nipa iku ti nwọn ti pinnu rẹ le mi lori, mo si ti di aladura. Işẹ aşọ-riran ti mo nkọ ni mo dojukọ, nkan buruku kan ko sisi lọkan mi mọ".




## BIBELI MIMỌ T'ỌRUN ỌWỌN IṢURA T'EMI

# Ẹ ni igbagbọ si Ọlọrun

**(Lati ọwọ Evangelist J. J. Akande 1, Ogbomọshọ)**

ỌRỌ ti a o fi ko ara wa l'ẹkọ loni ni ọrọ ti Jesu Kristi Oluwa wa sọ fun wa ninu Mark ori 11, ẹsẹ 22 bayi pe: "Ẹ ni igbagbọ si Ọlọrun". Ọrọ igbagbọ si Ọlọrun jẹ ẹyiti yio mu ki enia jogun ohun rere l'aiye yi ati lọrun pẹlu, bi enia ba le ṣe e.

Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba jẹ alaigbagbọ si Ọlọrun, o daju pe yio padanu oreọfẹ Ọlọrun l'aiye yi, yio si tun padanu iye ati ayọ ailopẹkun lẹhin aiye yi, nitorina ni a tun fi sọ fun wa ninu John ori 11, ẹsẹ 40, bayi pe, "Bi iwọ ba gbagbọ, iwọ yio ri ogo Ọlọrun."

### ILERI ỌLỌRUN

Nigbati Ọlọrun ko awọn ọmọ Israeli kuro ni ilẹ Egipti ninu oko ẹru, Ọlọrun ṣeleri fun wọn lati ko wọn de ilẹ ti o nṣan fun wara ati fun oyin, gẹgẹ bi Ọlọrun ti sọ ninu Eksodu ori 3, ẹsẹ 8, bayi pe, "Emi sọkalẹ wa lati gba wọn lọwọ awọn ara Egipti ati lati mu wọn wa si ilẹ rere ati nla, si ilẹ ti nṣan fun wara ati fun oyin."

Ṣugbọn anu ṣe wa lai ri i pe aini igbagbọ si Ọlọrun ko jẹki nwọn le de ilẹ ileri na, ninu ogunlọgọ awọn ti Ọlọrun ṣe ileri na fun, enia meji pere—Joshua ati Kalebu, ati awọn ọmọ wẹwẹ nikan ni nwọn jogun ileri rere na, gẹgẹbi a ti ri ọrọ na ka ninu Numeri ori 14: ẹsẹ 29-31, bayi pe:

"Oku nyin yio ṣubu li aginju yi, ati gbogbo awọn ti a ka ninu nyin, lati ẹni ogun ọdun lọ ati ju bẹ lọ, ti ẹ kun si mi. Ẹnyin ki yio de inu ilẹ na, ti mo ti bura lati mu nyin gbe inu rẹ, bikoṣe Kalebu ọmọ Jefune, ati Joshua ọmọ Nuni.

"Ṣugbọn awọn ọmọ wẹwẹ nyin, ti ẹnyin wipe yio di ijẹ, awọn li Emi o mu wọ ọ, awọn ni yio si mọ ile na ti ẹnyin gan."

### AINI IGBAGBỌ

Aigba Ọlọrun gbọ lo mu ki Ọlọrun binu bayi si



Evangelist J. J. Akande

wọn, eyi fihan pe aini igbagbọ ni ẹsẹ kini t'awọn ọmọ Israeli da si Ọlọrun, ti o si mu ki Ọlọrun binu si wọn.

Nitorina awa onigbagbọ akoko yi ni ọmọ Israeli ikẹhin, ti Ọlọrun si ṣe ileri fun wa lati mu de ijọba ọrun ninu ayọ ati iye ainipẹkun nipasẹ Jesu Kristi.

O yẹ ki a ṣora dada, ki aigbagbọ ma ba a mu ki awa na padanu Ibugbe Alafia Pipe na ti Ọlọrun ti pese silẹ fun wa lẹhin aiye igba diẹ yi.

Nitorina ni ọrọ Ọlọrun fi nsọ fun wa ninu Kronika Keji ori 20, ẹsẹ 20, bayi pe, "Ẹ gba Oluwa Ọlọrun nyin gbọ, bẹli a o fi ẹsẹ nyin mulẹ, ẹ gba awọn Woli Rẹ gbọ, bẹli ẹnyin o ṣe rere.

### Ẹ RONU

Ẹnyin enia Ọlọrun nibi gbogbo, ẹ ronu ileri ohun ti o ṣelẹ si awọn ọmọ Israeli iṣaju, bi aigbagbọ ti mu wọn padanu ileri Ọlọrun ti nwọn titori wọn ṣe, ko dapọ mọ igbagbọ ninu wọn.

Nitorina ni nwọn fi ṣegbe si aginju, gẹgẹ bi a ti ri i ka ninu Heberu ori 4, ẹsẹ 1-2, bayi pe, "Nitorina, ẹ jẹ ki a bẹru, bi a ti fi ileri ati wọ inu isimi Rẹ silẹ fun wa, ki ẹnikẹni ninu nyin ki o ma ba a dabi ẹnipe o ti kuna rẹ.

"Nitoripe a ti wasu Ihinrere fun wa gẹgẹ bi fun awọn na, ṣugbọn ọrọ ti nwọn gbọ ko ṣe wọn ni ire, nitori ti ko dapọ mọ igbagbọ ninu awọn ti o gbọ ọ."

Nitorina gbogbo ọrọ Ọlọrun ti awa Iranṣẹ Rẹ nwasu fun nyin, afi bi awọn ọrọ ati ẹkọ na ba dapọ mọ igbagbọ ninu nyin ni ẹ fi le de ilẹ Ọba ọrun.

Nitorina ni Isaiah ori 1, ẹsẹ 19, fi sọ bayi pe: "Bi ẹnyin ba fẹ, ti ẹ si gbọran, ẹnyin yio jẹ ire ilẹ na." Nitorina, "Ẹ ni igbagbọ si Ọlọrun."



# Itan oşupa (4)

*( Lati ọwọ S. L. Ogunniran, Ibadan )*

"E wo enia ti o jẹ talaka ati alaini, ti o ni aya ka nṣoṣo, şugbọn ti olowo ati ọlọrọ enia ti o ni aya pupọ de, ti o si gba ọkan şoşo ti o ni, ẹ ko ha mọ pe ọkunrin talaka yi ko ni ro ohun rere si ẹniti o gba a ni aya lọ?

"A! ẹnyin ọmọ enia oloye lori, ẹnyin ọmọran atata, ẹ ronu lori ọran ifẹ ki ẹ si ro ọrọ mi wo boya irọ ni mo pa. Ifẹ obinrin ti o sọ ile aiye di ohun to ngbona mọ ọmọ enia na ni o sọ ọmọ araiye di onişẹ ibi.

"Nitotọ, bi o ba pe, titi yio titi, ogun ọdun mbọ wa ku ọla. Enia ti o ba wa ni majeşin ni ode oni ki omaşe yọ ayọju nitori bi o pẹ titi, asiko ti a da yio to, a o si jẹ ipe Ọlọrun Ọba. Asiko ti Oşupa da fun awọn enia wọnyi dabi ala ni oju rẹ şugbọn b'ogun ọdun ni o ri loju awọn ti o nwaya.

"Nigbati oşupa ri pe asiko ti on da fun awọn enia wọnyi pe, o yọ oju si ode lati ma a ba gbogbo ẹniti o ba wa si ile rẹ sọrọ. Ifẹ Oşupa ti de bi gongo ọkan awọn enia wọnyi.

"A fi agbara ifẹ Oşupa wọ wọn li ọkan, nwọn dabi ẹniti a di ni igbekun nitori ifẹ, nwọn si ngba gulegule tẹle obinrin kiri bi obukọ. Nwọn ti sọ ile Oşupa di ile, nwọn ti sọ ọdẹdẹ rẹ di ọdẹdẹ, nwọn ko si kuro ninu ile Oşupa t'ọsan t'oru.

**ORUGBẸ IFẸ OŞUPA**

"Ko si oniruru ẹda alaaye ti orungbẹ ifẹ Oşupa ko gbẹ li ọkan nitotọ, nitori Oşupa lẹwa gidigidi. Ko si enia ti o le şe apejuwe ẹwa Oşupa, nko si rope a le ri arẹwa enia bi Oşupa mọ ni ori ilẹ aiye; bi a ba si ri iru rẹ lọrun a ko le ri eyiti yio daraju u lọ, nitori Oşupalẹwa gidigidi.

"Awọn ohun ẹlẹmi ati eyiti ko ni, gbogbo wọn ni ẹwa Oşupa ya lẹnu. Bi Oşupa ba nlọ ni ọna oko gbogbo ohun ẹlẹmi ti o ba ri i a ma fi iyin fun ẹwa rẹ. Bi ẹiyẹ ba ri i, nwọn a ma a fo tẹle e titi yio fi wọ ilu, nwọn a s ma a korin iyin ati ogo fun un. Nigbati Oşupa ba nkọja larin igbo, gbogbo ohun ẹlẹmi ti ko gbọdọ jade ni o ma njade, nwọn a si ti ipa bẹ ẹ ru ofin Ọlọrun Ọba.

"Okete a ma a wa lati woran Oşupa, ẹiyẹ Owiwi ti ko riran ọsan paapa a ma a wa lati wo ẹwa iyanu. Bi Oşupa ba nkọja lọ, ejo ti o jẹ ọta pataki fun ọmọ enia a ma a gbe ero ẹnu rẹ mi, a si ma a wọ lọ rere niwaju Oşupa-orekelẹwa obinrin. Nigbati awọn ohun ẹlẹmi ri ẹwa Oşupa yi, nwọn mu irohin lọ ba awọn ẹlẹgbẹ wọn ti ko ri Oşupa, gbogbo wọn si pinnu lati pe Oşupa pe ki o wa ki wọn ninu igbo ti nwọn ba le ri ogo ẹwa rẹ dada.

"Ki o to di pe ọjọ ibẹwo yi pe, awọn ẹranko ti şe eto nipa aye ti nwọn yio pese silẹ fun ibẹwo yi. Nigbati nwọn nşe eto "yi lọwọ awọn kan bẹ silẹ larin wọn, bayi ni: Kiniun dahun pe ki nwọn jẹki alejo na de si ile on nitoripe on ni Ọba atipe, bi alejo na ko ba de sibẹ yio jẹ ohun abuku ati ẹgan fun Ọba awọn ẹranko loju alejo na.

Awọn ẹranko tako aba yi, nwọn ko si gba fun Kiniun. Ọkan ninu wọn ti o jẹ ọyaju sọ pe, ọbun ni Kiniun işe, o ni bi afin rẹ ti tobi to ni, itọ ni o fi ba ibẹ jẹ, ati pe, bi enia ba de inu Afin na, anu ọmọ ẹda yio şe oluwarẹ nigbati o ba ri egungun ẹranko ti Ọba pajẹ bi o ti şe pọ to. Eranko na sọ pe bi awọn ẹranko ba gba iru imọran ti Kiniun da yi, yio jẹ abamọ fun wọn lẹhin ohun gbogbo.

(KOI TI PARI)

# Ilerin

(Lati oju ewe kejila)

ATAKUMASA si sọ pẹlu pe, Oloye Orisa na ni yio si wa ma a ba ọmọ on bọ orişa Orubutu na ni ọdọọdun.

Bayi ni ọrọ na ba fi di itan ni ilu Ilerin titi di oni-oloni yi ti nwọn fi nsọ pe:—"Orisa ni ẹniti o kọkọ tẹ ilu Ilerin do on ni ẹniti o si ti Erin wa.

Nigbati nwọn şe eyi tan ni awọn mejeji ba kuro nibẹ ti nwọn silọ si "Omi Ọmọ Mun" tabi "Munmun" ti ojina bi idamẹrin ibusọ si ilu Ilerin.

Nigbati nwọn de ibẹ, Atakumasa sọ fun Orisa pe, on fẹ sọ asọtẹlẹ kan fun un bayi pe, Oba Onilerin ti nwọn ba fi jẹ si ilu Ilerin, ko gbọdọ fi oju kan omi odo yi lailai tabi ki o mu ninu rẹ.

Lati ọjọ na lọ, Ọlọja ti o ba ti jẹ ni Ilerin ko gbọdọ ri odo yi tabi ki o mu ninu omi rẹ, şugbọn ni ọjọ ti Ọba na ba ku, omi na ni nwọn yio fi wẹ oku rẹ nitoripe, ni ọjọ ọjọ-kini, ọmọ ko mu ninu rẹ.

Omi na ni nwọn si ti fi nwẹ oku gbogbo awọn Onilerin ti o ti njẹ ni ilu Ilerin lati igbana titi fi di oni.

**IGBAKEJI ONILERIN**

Lẹhin gbogbo nkan wọnyi ni Atakumasa ati Orisa ba pada sile. Nigbati nwọn rin de "Okiti-ọmọwiwẹ o sọ fun Orisa na pe, Ọba ti o ba jẹ ni Ilerin, ti o ba mbọ lati Afin Ilesha, o nilati duro ni "Okiti-ọmọ-wiwẹ" yi, nibẹ ni awọn ara Ilerin yio si ti wa pade rẹ, nitoripe nibẹ ni ọmo ọn ti yyọọ ti o gb'okun.

Atakumasa pada si Afin rẹ ni Ilesha, Oloye Orisa si pada si Ilerin. Lati igbana ni Oloye Orisa ti nşe igbakeji Onilerin.

Lati igbati Atakumasa ti şe eto gbogbo nkan wọnyi tan, ti awọn ilana rẹ si ti fidimulẹ dada tan, ni awọn ara Ilerin ba fi nsun Lamọ ni ilu Ilerin bayi pe:—

"Ọmọ omi kan ti o ntinu ikoko şan, ti o sọ pe ki a ma pọn on la'de nile Ilerin. Okiti-abudi-babara, nwọn kọ f'ọmọ wiwẹ bọ mi suse. Okiti-abudi-babara, ti nwọn kọ f'ọmọwiwẹ bọ mi ya-yọyọ dabọ, Ibẹ lo ti sunkun jẹẹjẹẹ gb'ẹru, Ibẹ loti sunkun yọọyọọ gb'okun".

Olotu abọ mi re e o, digba.

# AKIYESI PATAKI

Ki ifọkanbalẹ le wa fun ẹniti o ba fi iwe irohin ikomọjade, isinku, igbeyawo, işile ati bẹbẹẹ lo şowọ siwa pe ki o jade ninu Iwe Irohin Yoruba. Bi o ba fẹ ki o jade ni ọranyan ki o kuku şe ni ipolowo ọja, şile kan abọ (1/6d) ni a ngba fun ọrọ marun fun apẹrẹ:— "Irohin koto afojuba ni aşeyẹ oku iya Moradeyọ ti o şe l'ọjọ kẹwa oşu yi". Eyi jẹ ọrọ mẹdogun, owo rẹ si jẹ sile kọọkanabọ ọna mẹta o jẹ sile mẹrinabọ (4/6). Bi o ba si ti pọ to ni owo rẹ yio fi pọ to. Ọrọ marun fun şile kan abo (1/6) ni.

OLOTU




